# IMỌRAN LATI ẸNU OGBOGI JAGUNJAGUN KAN SI ỌDỌMỌDE OLOGUN KAN

## 2 Timoteu 3:14-17; 4:1-8; 1 Timoteu 6:11, 12

## ẸKỌ 416 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Mã jà ija rere ti igbagbọ́, di iye ainipẹkun mu inu eyiti a gbé pè ọ si, ti iwọ si ṣe ijẹwọ rere niwaju ẹlẹri pupọ̀" (1 Timoteu 6:12).**

**I Imisi Iwe Mimọ́**

1 A gba Timoteu ni iyanju lati duro ninu nnkan wọnni ti o ti kọ́, 2 Timoteu 3:14

2 Iwe Mimọ́ le sọ ni di ọlọgbọ́n si igbala nipa igbagbọ́, 2 Timoteu 3:15

3 Gbogbo Iwe Mimọ́ ni a fi fun ni nipa imisi Ọlọrun, o si ni erè, 2 Timoteu 3:16, 17

**II Aṣẹ Ti O Ni Ọ̀wọ̀**

1 A pa a laṣẹ fun Timoteu niwaju Ọlọrun ati Jesu Kristi lati waasu Ọrọ naa, 2 Timoteu 4:1, 2

2 Akoko yoo dé nigba ti awọn eniyan ki yoo le gba ẹ̀kọ́ ti o yè kooro, 2 Timoteu 4:3, 4

3 A gba Timoteu niyanju lati ṣe iṣẹ-iranṣẹ rẹ̀ laṣepe, 2 Timoteu 4:5; 1 Timoteu 6:11, 12

**III Ade Ti A Fi Lelẹ**

1 "Atilọ mi si sunmọ etile," 2 Timoteu 4:6

2 "Emi ti jà ija rere," 2 Timoteu 4:7

3 "A fi ade ododo lelẹ fun mi," ki i si ṣe kiki "emi nikan," 2 Timoteu 4:8

### ALAYE

Awọn ọ̀rọ ẹ̀kọ́ wa yii ti mu ni lọkàn tó! Paulu Apọsteli alagba ninu iṣẹ Ọlọrun ti fi imọran idagbere fun Timoteu, alufaa kekere, ẹni ti o ṣi ni akoko pupọ niwaju rẹ̀ lati lò fun iṣẹ Ọlọrun. Paulu Apọsteli paapaa bẹrẹ iṣẹ ìsin rẹ̀ bi Onigbagbọ nigba ti o wà ni ọ̀dọ́, o si fi gbogbo iyoku igbesi ayé rẹ̀ fun iwaasu Ihinrere Jesu Kristi Oluwa. Ọpọlọpọ ewu, inira, inunibini ati ipọnju ni o dojukọ ọ ninu gbogbo iṣẹ-iranṣẹ rẹ̀ ati nikẹyin a fi i sinu tubu nibi ti o ti n reti ati kú gẹgẹ bi ajẹrikú. Paulu kò wi fun Timoteu pe ijagun oun paapaa bi Onigbagbọ yoo ni ìrọrun. Bi a ba wo o nipa ti ara, ọrọ wọnyii ki i ṣe ohun ti o le mú iṣiri bá Timoteu bi ọ̀kan ninu awọn ẹni ti yoo gba ipò Paulu, ṣugbọn gbogbo ifojusọna ẹnikẹni ti o ba mura tán lati sin Ọlọrun ni lati jẹ́ nipa ti ẹmi. O ni lati wo awọn nnkan ti o wà loke, ki i ṣe eyi ti o wà ninu ayé.

Ipè Onigbagbọ́ ki i ṣe fun iṣẹ ode ara bi ko ṣe si ogun jija; o ni lati jẹ́ ọmọ-ogun, ki i ṣe oniṣowo; o ni lati farada inira ki i ṣe irọrun, igbesi-ayé rẹ̀ ni lati jẹ́ ti ìsẹra-ẹni, ki i ṣe ti itẹra-ẹni lọrùn. Alagba Apọsteli yii le ṣe akotan igbesi-ayé rẹ̀ pẹlu awọn ọ̀rọ wọnyii: "Emi ti jà ija rere, emi ti pari ire-ije mi, emi ti pa igbagbọ́ mọ́." O le gboju soke si Ọrun fun erè didan ti o si daju; nitori eyi ọrọ kọọkan ti o fi gba Timoteu ni iyanju (ati awa naa pẹlu) jẹ́ iṣiri ati imisi nipa ti ẹmi.

**Imisi**

Timoteu ọdọmọdekunrin naa ṣe oriire pupọ nitori lati igba ọmọde ni a ti kọ́ ọ bi Iwe Mimọ́ ti jẹ́ otitọ bi o ti niyelori to; eyi ti o le sọ ni di ọlọgbọn si igbala nipasẹ igbagbọ́ ninu Kristi Jesu.

Bibeli ti a fi aṣẹ si lati ọwọ́ "King James" eyi ti awa n lò ti a si fẹ́ ki gbogbo eniyan maa lò, wi bayii pe "Gbogbo iwe-mimọ́ li o ni imisi Ọlọrun." A kò gba ni ni imọran lati lo Bibeli ti a n pè ni "American Standard Version" eyi ti o sọ bayii pe "Gbogbo iwe mimọ́ ti Ọlọrun mi si," a fo ọrọ yii "li o ni." Fifo ọrọ yii fi aafo silẹ lati rò pe awọn Iwe Mimọ́ kan wà ti kò ni imisi Ọlọrun. Pupọ eniyan ni yoo fẹ́ ki a gbagbọ́ pe ki i ṣe gbogbo Iwe Mimọ́ ni o ni imisi; ṣugbọn bi ibeere yii bá jade pe awọn wo ninu Iwe Mimọ́ ni kò ni imisi, ta ni yoo ṣe ipinnu lori eyi ti o ni imisi ati eyi ti kò ni? Laisi iyemeji a le mú iduro wa lori "King James Version" gẹgẹ bi Ọrọ Ọlọrun ti o ni imisi. Ninu eyi awa ni idaniloju, ọkàn wa si balẹ. Ojuṣe wa ni lati gba Ọlọrun gbọ́ gẹgẹ bi Ọrọ Rẹ̀ ti wí.

“Gbogbo iwe-mimọ́ li o ni imisi Ọlọrun o si ni ère fun ẹkọ́, fun iba-ni-wi, fun itọ́ni, fun ikọ́ni ti o wà ninu ododo.” Otitọ awọn ọrọ̀ wọnyii n dún bi agogo. Kò si tabi-tabi ninu rẹ̀. Kalamu ti o kún fún imisi mimọ́ ni idaniloju ti kò le yipada. Ọrọ Ọlọrun ni o lọla, ti o si ga jù lọ fun wa. On ni opin aṣẹ, ile ẹjọ kanṣoṣo ti a le fi ẹjọ wa sùn. Bi a bá ni iyọnu ninu tabi lode, a le lọ sinu Ọrọ Ọlọrun lati wá itunu ati idasilẹ, ohunkohun ti iyọnu naa jẹ́. Gbogbo Iwe Mimọ́ wà fun ilo wa lati pese wa silẹ patapata fun iṣẹ rere gbogbo.

**Diduro Ninu Ihinrere**

Ikilọ ti a fun Timoteu lọ bayii pe, “Iwọ duro ninu nkan wọnni ti iwọ ti kọ́, ti a si ti jẹ ki oju rẹ dá ṣáṣa si.” Njẹ ikilọ yii kò wà fun awa naa pẹlu lọjọ oni? Dajudaju o wà fun wa. Ki ni Ọrọ Ọlọrun kọ́ wa, ki si ni awọn ẹkọ Ihinrere ti a kọ́? A ti kọ́ nipa agbára otitọ Ọlọrun ayeraye ati bi o ti jẹ́ mimọ́ laulau. A ti kọ́ bi o ti ṣe ohun danindanin tó pé a kò gbọdọ gbọ̀jẹgẹ́ pẹlu ẹ̀ṣẹ ayé, tabi ki a yapa kúrò ninu otitọ Ọlọrun. A ti kọ́ bi a ti ni lati fi gbogbo ayà wa jẹ́ oloootọ si Ọlọrun. A ti kọ́ bi a ti ni lati jẹ́ oloootọ si ìlanà ti a di mu nigba ti a jọ̀wọ̀ ọkàn ati ayé wa fun Ọlọrun. Kò tó lati kọ́ ati lati mọ Iwe Mimọ́ nikan; ṣugbọn lati gba erè ikẹyin, a ni lati duro a si ni lati ṣe awọn nnkan wọnni ti a ti kọ́, ti a si ti jẹri rẹ̀.

**Opin Irin-Ajo**

Paulu n bọwa si opin irin-ajo rẹ̀. Awọn ẹsẹ ẹ̀kọ́ wa wà lara awọn ọrọ̀ rẹ̀ fun ijolootọ rẹ̀ si otitọ ti a ṣi paya fun un nigba ti o bá Jesu pade lọna irin-ajo rẹ̀ si Damasku. O jẹ́ ọdọmọdekunrin nigba naa. Nisisiyii o ti di Paulu arugbó. O ti ja ogun pupọ, o si ti farada iṣoro pupọ. O le sọ fun Timoteu pẹlu idaniloju pe ki o maa “farada ipọnju.” Timoteu ni lati ni ireti pe wahala yoo dojukọ oun; ipọnju yoo si wá sọna rẹ̀; bẹẹni o daju pe yoo ni ọ̀tá. “Nitõtọ, gbogbo awọn ti o fẹ mã gbé igbé iwa-bi-Ọlọrun ninu Kristi Jesu, yio farada inunibini” (2 Timoteu 3:12). Pupọ inunibini ti o dide si Paulu wá lati ọdọ awọn ti n farahàn bi eniyan Ọlọrun. O jiya lọwọ awọn eke arakunrin. Ṣugbọn o wi pe “a nfi mi rubọ nisisiyi … Emi ti jà ija rere.” A fẹ fi i rubọ nitootọ. O fi ẹjẹ rẹ̀ ṣe edidi ẹri rẹ̀. O ti gba ade ti o n sọrọ nipa rẹ̀, ti Oluwa yoo fun gbogbo awọn ti o fẹran Rẹ̀.

“Emi ti pari ire-ije mi, emi ti pa igbagbọ́ mọ́.” Eyi ni aṣiiri aṣeyọri awọn Onigbagbọ́ ninu ayé yii, lainaani ohunkohun ti yoo gbà. Ọrun kò wọn ni iyekiye. Bi a ba fẹ wọ Ọrun, a ni lati pa igbagbọ́ mọ́. A gbọdọ tẹ̀ siwaju lati maa rin ninu imọlẹ. A gbọdọ tẹ̀ siwaju si opin ire-ije nì ti ipe iga ti Ọlọrun ninu Kristi Jesu. Ija lati ibẹrẹ de opin ni eyi, Paulu pe e ni “ija rere.” O jẹ́ ija rere fun Paulu nitori ti o fi ọwọ danindanin mú igbagbọ́ nì ti a fi le awọn eniyan mimọ́ lọwọ lẹẹkanṣoṣo.

**Ija Igbagbọ́**

Onigbagbọ gidi jẹ́ ojulowo ọmọ-ogun. Niti pe Ọrọ Ọlọrun wi pe, “ja,” eyi tumọ si pe idojukọ wà; atako ati ọta wà ti a gbọdọ bá jà. Ọta wa ki i ṣe ara ati ẹjẹ, ṣugbọn gẹgẹ bi Ọrọ Ọlọrun ti sọ fun wa, alaṣẹ agbara oju ọrun ni -- eṣu.

“Di iye ainipẹkun mu.” Ki ni iye ainipẹkun? “Iye ainipẹkun na si li eyi, ki nwọn ki o le mọ̀ ọ, iwọ nikan Ọlọrun otitọ, ati Jesu Kristi, ẹniti iwọ rán” (Johannu 17:3). Njẹ iwọ mọ Ọlọrun? Ọna kanṣoṣo ni o wà ti a le fi mọ Ọlọrun: “Nipa eyi li a si mọ̀ pe awa mọ̀ ọ, bi awa ba npa ofin rẹ̀ mọ́” (1 Johannu 2:3). Ẹnikẹni kò le mọ Ọlọrun bi ko ba pa gbogbo ofin Rẹ̀ mọ́. Eyi ki ṣe ofin kanṣoṣo - ṣugbọn ó gbọdọ pa **gbogbo** wọn mọ́. O le maa ya awọn miiran lẹnu bi o ṣe le ṣeeṣe lati pa gbogbo ofin Ọlọrun mọ. Bibeli wi pe: “Ki iwọ ki o fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo inu rẹ, fẹ́ Ọlọrun Oluwa rẹ. Eyi li ekini ati ofin nla. Ekeji si dabi rẹ̀, Iwọ fẹ ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ” (Matteu 22:37-40). Jesu wi pe, “Ninu awọn ofin mejeji yi ni gbogbo ofin ati wolĩ rọ̀ mọ́.”

Ija rere ni eyi! Bi iwọ kò ba jẹ́ ọmọ-ogun rere iwọ ki yoo le ja ija rere. O si wi pe, “Farada ipọnju.” Bi iwọ ba lero pe a o gbé ọ lọ si Ọrun lori ibusun oniyẹ, iwọ n tan ara rẹ jẹ. Yoo gbà ọ ni ohun gbogbo ti o ni, ati bori gbogbo rẹ̀, oore-ọfẹ Ọlọrun, lati jẹ́ Onigbagbọ́! Ọlọrun wi pe ire ije ki i ṣe ti ẹni ti o yara, bẹẹni ogun ki i ṣe ti alagbara. Kò di igba ti eniyan lagbara koko ki o to le di ọmọ-ogun rere ti Kristi. Bẹẹni kò di igba ti o ba le sare bi ehoro ki o to le bori ninu ire ije yii.

**Ojuṣe Ojiṣẹ Ọlọrun**

Gbogbo ojiṣẹ Ọlọrun tootọ ninu Ihinrere ni o n waasu ẹkọ Ọrọ Ọlọrun ni ẹkunrẹrẹ ni mimọ́ ati pẹlu agbara. Aṣẹ mimọ́ ti Paulu pa fun Timoteu lati “Wasu ọ̀rọ na,” kò wà fun Timoteu nikan. Aṣẹ ọlọwọ yii wà fun olukuluku ojiṣẹ Ọlọrun ninu Ihinrere.

Eniyan le ṣai jẹ alufaa ti n waasu lati ori aga iwaasu, ṣugbọn Onigbagbọ́ tootọ kọọkan ni o jẹ́ alufaa ni ti pe o jẹ́ ọmọ-lẹyin onirẹlẹ ara Nasarẹti nì. Igbesi-ayé ti eniyan n gbé ni yoo waasu tabi tako Ẹsin Igbagbọ́. Igbesi-ayé eniyan ati ẹ̀kọ́ ti o fi n kọ́ ni ni lati wà ni idọgba pẹlu otitọ Ọrọ Ọlọrun.

Ninu 2 Timoteu 4:2, a kà nipa ojuṣe awọn oniwaasu. O gbọdọ kede awamaridi ọ̀rọ Kristi. Iwaasu rẹ̀ ni lati wà lori awọn ẹsẹ wọnni ninu Ọrọ Ọlọrun ti o n fun ni ni iṣiri, ti n sọniji, ti o si n fun ni ni imisi; iwaasu rẹ ni lati wà lori awọn ẹsẹ nì ti o n tú aṣiiri ẹ̀ṣẹ, eke ati ẹ̀tan ti o wà ninu igbesi-ayé awọn eniyan. Apọsteli naa fi kun un pe: “Nitoripe igba yio de, ti nwọn ki yio le gba ẹ̀kọ́ ti o ye koro.” Njẹ akoko kan ti wà ti a ti i mu Ọrọ Ọlọrun yii ṣẹ ju akoko ti a wà lọjọ oni?

**Akokò Ti O Wọ̀**

“Ṣe aisimi li akokò ti o wọ̀, ati akokò ti kò wọ̀.” Paulu Apọsteli lo anfaani ati akoko ti o ṣi silẹ fun un lati waasu Ihinrere ati lati jẹri igbagbọ rẹ̀ ninu Kristi Jesu. Laisi tabi-tabi bi ọgbọ́n ti ṣe danindanin, bẹẹni itara ṣe danindanin, ṣugbọn “akokò ti kò wọ̀” fun awọn kan le jẹ “akokò ti o wọ̀” bi o ba ṣe ti Ọlọrun ni. Fẹliksi feti si Paulu nipa igbagbọ́ ninu Kristi. Fẹliksi wariri o si dahun pe, “Mã lọ nisisiyi na; nigbati mo ba si ni akokò ti o wọ̀, emi o ranṣẹ pè ọ” (Iṣe Awọn Apọsteli 24:25). Nisisiyii ni “akokò ti o wọ̀” fun Ọlọrun: “Kiyesi i, nisisiyi ni akokò itẹwọgbà; kiyesi i, nisisiyi ni ọjọ igbala” (2 Kọrinti 6:2). Yoo ṣe anfaani lọpọlọpọ bi awọn Onigbagbọ́ ba kede Ihinrere ti igbala wọn nigbakugba ju ti atẹyinwa lọ.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni Timoteu ni lati ṣe pẹlu Iwe Mimọ́ ti o ti kọ́?

2 Nigba wo ni Timoteu ti kọ́ Iwe Mimọ́?

3 Iwe Mimọ́ wo ni a fun ni nipa imisi Ọlọrun?

4 Sọ mẹrin ninu awọn nnkan wọnnì ti Iwe Mimọ́ ti ni ère.

5 Ki ni o ṣẹlẹ si awọn eniyan ti kò le gba ẹ̀kọ́ ti o yè kooro?

6 Njẹ igbesi-ayé Timoteu bi Onigbagbọ jẹ́ ti irọrun tabi ti iṣoro?

7 Bawo ni Paulu Apọsteli ti ṣe akotán igbesi-ayé rẹ̀?

8 Ki ni a fi silẹ de Paulu? Ta ni o fun un ni èrè yii?

9 Ta ni yoo gbà iru ère bẹẹ?